# THE YORUBA NEWS,

FOR GOD, THE KING & THE PEOPLE.

VOL. XIII, No. 47 New Series — IBADAN, TUESDAY — DECEMBER 12TH 1939 — PRICE ONE PENNY


# IROHIN OGUN LATI ILU OYINBO

## APA KEFA.

1. O di ọsẹ kẹrin ti a ti tẹwe irohin ogun ikẹhin sode. Ni gbogbo akoko yi, ogun jija lori ilẹ lärin Franse ati Jamani ni ipinlẹ wọn ko ni iyọri pataki kan. Ko dabi ẹnipe ogun tiwa tabi ti awọn Jamani yi gbidanwo ija nla kan fun iwọn ọsẹ mẹrin si i nigbati ojo ijọ o kun fun ọjọ ati yinyin. O jẹ Franse ati Gẹsi lọrun lati di bode wọn bi siyi mu, ki wọn si tubọ mã ko irinsin ija wọn jọ si i, nigbati o jẹ pe awọn Jamani yio tubọ mã jiya aini irinsin ijagun wọnyi lọwọ.

2. A ko ye ri irohin aisi itẹlọrun fun awọn ara ilu Jamani gba. Awọn ara Czech, ilu awọn ti Jamani fi agbara gba niwọn ẹsin, ko dẹkun fifi awọn Jamani lape niwọn bi ipa wọn ti mọ, awọn Jamani nã si nfi iwa ika ati ipaiya nla tẹri isọtẹ gbogbo ba.

Ẹgbẹfa ọdọmọkunrin awọn akẹkọ ọlọgun mejidinlogun titi lo de ọkọdun mejilelogun ti ilu nã ni awọn Jamani ko, ti wọn ti yinbọn pa apakan wọn, ti nwọn si ko awọn yoku da sinu ọgba ẹwọn.

3. Ni ọsẹ kẹta sẹhin ni HITLER lọ si apejọ kan ti nwọn se ninu ile imuti abẹlẹ kan ni Munich, ilu ibiti ero dida ẹgbẹ NAZI silẹ kọ bẹrẹ. HITLER tete kuro ninu apejọ na siwaju akoko ti iba kuro nibe; bi ogbọn iṣẹju lẹhinna ni pakute afọnja ti nwọn ti kẹ silẹ nibẹ gbina ni ibiti HITLER gbe ti duro si (nigbati o fi mba wọn sọrọ.) o pa enia mẹfa ni apafọn, o si pa ọpọlọpọ lara. Boya eyi le jẹ ãba awọn ara Jamani ti wọn lodi si i lati pa HITLER tabi ete awọn ọmọ-ẹhin rẹ lati jeki awọn enia mã ba a darọ.

4. HITLER mọ aini anfani nlanlà rẹ loju okun, o si ti nfi ikanra gbidanwo ati mã dubo awọn ọkọ ti nko ipese lọ si ilu Franse ati ti Gẹsi. Awọn ọkọ abẹ-omi rẹ ko ṣe ori-ire tobẹ torina li o ṣe mu inkan ipaiya mi jade. Awọn ọkọ ofurufu ti Jamani ni nwọn ti nsọ awọn afọnja omi sinu okun. O si ti jẹ ofin Ogun jija ti a mọ tẹlẹ pe a ni lati fi idakọro so awọn afọnja omi wọnyi mọlẹ ninu okun ki a si jẹki awọn ilu ti wọn ko lọwọ ninu ogun mọ ibiti wọn wa. Ṣugbọn Jamani ko fi idakọro so awọn afọnja omi wọn mọlẹ. Ibikibi ni iṣàn ngba wọn lọ kakiri ninu okun, nwọn si jẹ ohun ti ọkọ awọn ilu ti ko lọwọ ninu ogun pẹlu ti Franse ati ti Gẹsi le kọlu. Ni tootọ, ọkọ awọn ilu ti ko lọwọ ninu ogun ti wọn ti ri nipa kikọlu afọnja omi wọnyi pọju awọn ọkọ Franse ati ti Gẹsi ti o ri lọ.

5. Gẹsi ati Franse si ti pinnu ati fi ogundi gun nipa yiyọ owo bile si Jamani. Latẹhinwa ni awọn ọkọ ogun wa ti nfi agbara gba awọn ẹru ti nti awọn ilu mi lọ si Jamani. A ko si gbidanwo ati da awọn ẹru ti nti Jamani lọ si awọn ilu ti ko lọwọ ninu ogun duro. Ni saà ti inabọ a o se eyi nã pẹlu. Nipa bẹ a o di Jamani lọwọ ifi ọja tita wọn sọwọ si awọn ilu ti ko lọwọ ninu ogun; nipa bayi wọn ko ni le ri owo lo fun ati mã jagun nã lọ. Ọna yi le bà òwò awọn ilu ti ko lọwọ ninu ogun jẹ, ṣugbọn ko mu ibajẹ pupọ wa bi ọna ti awọn Jamani tẹle ti o fa riri ọkọ awọn ilu ti ko lọwọ ninu ogun nipa afọnja omi dani.

6. Ninu ija ofurufu, o han gbangba pe ipa wa bo ti awọn Jamani mọlẹ. Awọn ọkọ ofurufu Jamani ti gbidanwo niye igba lati da afọnja lu ebute Gẹsi ati lati ya aworan (*photo*) awọn ilẹ etikun Gẹsi. Ninu igbidanwo wonyi, o di ọkọ ofurufu Jamani mẹtalelogun ti a ti fi agba ja dasilẹ. Awọn ọkọ ofurufu Gẹsi ati ti Franse ti fo koja lori ilu Jamani nigba pupọ ninu ipalara kinnn tabi laisi adanu ọkọ ofurufu tiwa kan rara.

7. Ni ọsẹ ti o kọja, diẹ ninu awọn ọkọ ofurufu ti Gẹsi fi igboiya nlanlà fo lọ si ibiti awọn Jamani gbe ko ọkọ ofurufu ti oja okun wọn jọ si ti a npe ni Borkum. Ọkọ ofurufu wọnyi ba awọn ogun Jamani ni ẹbaãbu pẹtapẹta nwọn fo ni ibambalẹ ẹsẹ mẹfa si ilẹ-lẹ, ti wọn si nrọ agba awọn da ọnọ-mọsini lu awọn ãgba nla Jamani ati awọn ọkọ ofurufu ti o wa nibẹ, ti nwọn si ṣe nwọn lofo lọpọpọlọ.

8. Ijọjọpọ gidigidi ni iwà awọn ara Russia ko ba iṣelu ti awọn orilẹ-ede miran. Ẹ ti ka a ninu iwe kẹji irohin yi bi ogun Russia ti rọ wọ ilu Polandi lọ ati bi Jamani pẹlu Russia ti ṣe pin ilẹ Polandi larin arawọn. Ṣugbọn Gẹsi ati Franse ko ni ija pẹlu Russia, o si dabi ẹnipe Russia yio jẹ ewu nla fun ilu Jamani ju bi wọn ti le jẹ fun wa lọ.

9. Nisisiyi Russia ti mbere awọn inkan mi si i lọwọ awọn ilẹ kekeke, o nfẹ lati mu ki ipo rẹ lagbara. Russia ti bere awọn inkan diẹ lọdọ Finlandi, ilu kan ni iha Ariwa-Iwọ-orun Russia. Ninu awọn ibere wọnyi ni goigia awọn etikun ti mbẹ ni eti awọn ilẹ etikun Finlandi wa, ati pe ki Finlandi ba ilu Russia ṣe adehun iṣọwọpọ fun àbo. Awọn ara Finlandi ko le gba ibere wọnyi, Nisisiyi Russia ti ko ọmọ-ogun rẹ wọ inu ilu Finlandi lọ ati pe awọn ọkọ ofurufu ti Russia ti nrọjo afọnja si awọn ilu nlanla ni Finlandi eyi ti o mu ọpọ iparun ati ofo ẹmi pupọ lọwọ.

10. Anu awọn ara Finlandi ṣe Gẹsi ati Franse ṣugbọn a ko ba wọn ni adehun ati ran wọn lọwọ, ko si dabi ẹnipe a le ṣe bẹ. Bi o ti wu ki a ṣe ainí idunnu si awọn iwa Russia to, a gbagbọ pe Russia ati Jamani ko le jẹ ọrẹ danmọran, ati pe wiwọ ti awọn ara Russia wọ ilẹ Polandi ti ṣegun ero ati tan siwaju si iha Ila-orun fun awọn ara Jamani.

11. Adapọ Ilu Amẹrika ṣi wa ni silọwọ si ogun yi, ṣugbọn nwọn ti tubọ fi aini ti o daju gbangba han pe wọn ni anuyan si awọn Olugbeja. Nwọn da awọn Ẹgbẹ silẹ ti yio mã fun wọn ni ọja didi ọgbẹ, egbogi ati awọn ohun-elo ile-iwosan fun Gẹsi ati Franse ninu ogun yi. A ni ireti ati tẹ irohin Ogun mi titi ọsẹ meji si i

Adura wa ni pe ki ise olukuluku nyin fun u ni ayọ ni ọdun yi.

Opolopo ti mhin awọn oluko wọn fun awọn obi wọn—boya fun rere tabi fun buburu, ṣugbọn nina ọdun yi ni iwọ o fi Ile-Iwe silẹ ti iwọ ti irohin rẹ tabi iwa rẹ

Arakunrin ọwọn, iyatọ pupọ ni o wa larin Ile-Iwe ati Ile-Iṣe. Gẹgẹ bi ẹ ti mọ akoko tabi igba ti Ẹyin (Eggs) Ẹfọn (Mosquitos) ngbà ki o to yi pada si tanwiji (Larva) ati lati Larva si (Pupa) ati bẹbẹ Arakunrin, ki iṣe pe enikan ni o nyi ẹyin yi pada bikoṣe igba tabi akoko. Bẹ gẹgẹ ni ọmọ enia ni igba tabi akoko tirẹ (Stages of life) ni ode aiye.

Nitorina a fẹ ki o han si nyin gbangba pe iyipada kan larin igbesi aiye ọmọ enia ni eyi. (Lati Ile-Iwe si Ile-Iṣe) O si ni lati jẹ ohun titun ni oju ẹnyin arakunrin wa, nitori ẹ ṣẹṣẹ fi ẹsẹ si ona ni ṣiṣẹ ni

Ni ona titun yi ko si ẹgbẹ [whip] ṣugbọn ẹṣẹ [fine] wa fun aṣiṣe ati bẹbẹ. Gẹgẹ bi ẹ ti nbẹru fun ẹgba bẹ na ni ẹ ni lati mã bẹru ẹṣẹ na.

Ni ọna yi ni o ni lati fi iwa ewe silẹ ki o si mã hu iwa agbà ti yio jẹ apẹrẹ rere fun awọn ti o nbọ lẹhin.

Arakunrin ọwọn, ni akotan nihin ni enia ti mbẹrẹ si iru aiyẹ [Responsibilities] rẹ eyiti awọn obi rẹ ti nru fun u lati igba ewe rẹ wa. Nigbayi ni enia to nmọ akoko ti owo wọn tabi pọ, akoko ti onjẹ wọn tabi pọ, tabi ti enia nkọ lati pa inkan mọ nigba ọpọ di akoko ọwọn ati bẹbẹ.

## AKIYESI TI IJỌBA.

Ijọba kede pe, ẹnikẹni ti o ba fẹ kọ iwe si ilu oibo ati awọn ilu mi ti mbẹ ni ẹhin okun tabi ẹhin odi Nigeria ni lati kọ orukọ ara rẹ, ibiti o ngbe ati ilu ti o wa, si oke ẹhin apo iwe ti yio fi ranṣẹ, pẹlu orukọ ẹniti o nfi iwe na ranṣẹ si bi ko ba ṣe bẹ ẹ iwe na ko ni lọ laṣeko.

## ẸRAN D' ONI-PA-NṢARA.

A dupẹ lọwọ awọn Alaṣẹ ilera wa fun iyipada rere ti a kiyesi nipa bi awọn ẹlẹran ti ṣe nta a kiri larin ilu nisisiyi ati bi nwọn ti ṣe nta a ri.

Latijọ, awọn ẹlẹran nta a kiri lai fi ohun kan kan bo ẹran nwọn, ṣugbọn ni isisiyi nwọn ti nfi ate Pàṣárà bo o.

### A DANGEROUS BUILDING.

Along Ogunmọla Road, near a stream at Isalẹ Ajọbọ now stands an old Storey house in a dangerous condition. The foundations have been sagged in various places and the walls are likely to fall down with the roof at any time.

In the interests of passers-bye, we trust the authorities will get this source of danger rectified in time before the rainy season sets in.

## News & Notes

Mr. Robert Jones the Native Administration Engineer has returned from furlough looking the picture of Health. We say: "E Kabọ"

The setting up of electric lighting posts and the laying down of water supply pipes in the town are proceeding steadily.

The Cambridge Local Examinations which began last week Monday at the Ibadan Grammar School is still proceeding.

Wishing the participants all success.

It is noticeable that owing to shortage of the latter rains, the dry season maize crop is 70% a failure this year.

## Do Not Let Them Charge You More.

The middle column gives the maximum retail prices allowed by Government in Lagos. Check up on these prices when you shop, and make sure you are not being charged more. No shop may sell above these prices although it may sell below them.

In view of complaints which are current regarding the rise of retail prices since the war started the following points should be noted:—

| | | |
|---|---|---|
| Ballam Rice | — | No rise. |
| White Rice | — | No rise. |
| Sugar in packets | — | No rise. |
| Ideal Milk | — | Slight rise 3/9 to 4/. |

Salt has gone up from 7/9d to 9/—. There are indications that petty traders are hoarding this as sales have been abnormally high and the firms are short of supplies.

It must be remembered that freight and insurance rates have risen considerably, so that in cases where there is no rise the firms are making less profit than before the war.

Flour has risen from 1/2d to 1/4d per 5lb. bag. In this case the depreciation of the pound (i.e.) the higher cost of American dollars) is largely responsible, a matter over which the firms have, of course, no control. The same applies to Cabin Bread, which has risen from 11½d. to 1/1d. per dozen.

### FOOD PRICES.

The following are the maximum wholesale and retail prices on 8th November, authorised in Lagos, of the articles set out below, calculated in accordance with Regulation 2 of the prices of Imported Food Regulations, 1939.

| | WHOLESALE PRICE | RETAIL PRICE. | Pre-War Retail Price |
|---|---|---|---|
| BUTTER<br>fresh New Zealand<br>English<br>Beck's tinned | per dozen 1 lb tins 18/- | per lb 2/5d<br>„ „ 2/6d | |
| FLOUR | per 95 lb bag 24/3<br>per 49 lb bag 12/6<br>per 10-10 lb bags 25/-<br>per 20-5 lb bags 25/- | per 10 lb bag 2/8d<br>per 5 lb bag 1/4d | 2/3<br>1/2 |
| RICE (Ballam) | per 2 cwt bag 32/-<br>per 10-20 lb bags 30/-<br>per 10-10 lb bags 15/10<br>per 10-5 lb bags 8/4 | per 20 lb bag 3/3½<br>per 10 lb bag 1/8d<br>per 5 lb bag 11d | 3/3<br>1/6<br>11d |
| RICE (White) | per 2 cwt sack 30/-<br>per 10-20 lb bags 27/6<br>per 10-10 lb bags 14/1 | per 20 lb bag 3/-<br>per 10 lb bag 1/6 | 3/-<br>1/5 |
| SALT | per ton £10 7 6d. | per 90 lb bag 9/- | 7/9 |
| SUGAR, in packets | per case of 112-1 lb packets 28/- | per 12-1 lb packets 3/ | 3/- |
| loose | per case of 25 kilos 13/9 | per lb 3d | |
| MILK, Ideal Brand | per case 96 tins 31/- | per 12 tins 4/- | 3/9 |
| CABIN BREAD | per case 24 doz pkts 23/6 | per doz 1/1d | 11½d |
| CORNED BEEF | per case of 48-12 oz. tins 23/-<br>per case of 96-8 oz tins 34/- | per 12-12 oz tins 6/3<br>per 12-8 oz tins 4/6 | 5/6<br>4/3 |
| QUAKER OATS | per case 36 tins 44/-<br>per case 72 tins 49/6 | per doz 15/6<br>per doz 8/6 | 11/6<br>6/6 |

The maximum prices prevailing on 24th November will be published later. The above prices are for Lagos only.

